# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**SÍSOPỌ̀ MỌ́ ONÍṢẸ́GÙN NLÁ**

Ìjẹ́wọ́ - Ifìhàn 12:11: Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Agùntàn na, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní títí dé ikú.

Ní orúkọ Jésù Krístì, mo jẹ́ ayànfẹ́ ọmọ Ọlọ́run. Mo gbàgbọ́ nínú Ọlọ́run, mo gbàgbọ́ nínú Jésù Krístì, mo gbàgbọ́ nínú Ẹ̀mí Mímọ́ Olùbùkún T'ó n gbé nínú mi. Mo gbàgbọ́ nínú agbára ayérayé, tíkò lè yẹ̀, tówà nínú ọ̀rọ̀ Ọlọ́run. Mo gbàgbọ́ wí pé, ikú àti ìyè wà nínú ahọ́n mi. Mo gbàgbọ́ wí pé, bí mo ṣe nṣe ìjẹ́wọ́ yì sí ìyè, pẹ̀lú agbára tówà nínú ahọ́n mi, gẹ́gẹ́ bí àwọn ọ̀rọ̀ tí Ọlọ́run fi sí ẹnu mi, èmi yóò ṣerere. A ti kọ́ ọ́ pé Jésù Krístì fi ẹ̀jẹ̀ Rẹ̀ sílẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ohun mímu àti ẹran Rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí oúnjẹ, wí pé, ẹnikẹ́ni tóbá mu ú, tósì jẹ ẹ́ kì yóò kú títí láí. Ní báyì, pẹ̀lú igbàgbọ́ líle nínú ọkàn mi, mo mú ife tí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Agùntàn Ọlọ́run wà nínú rẹ̀ dání, mo sì mu ú, kí n bà lèní ìyè aìnípẹ̀kun. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ náà fọ̀ jáde kúrò nínú mi gbogbo ìrúgbìn àjogúnbá ibi tàbí àfọwọ́fà tó nbẹ nínú mi. Jẹ́ kí ó fọ ìṣàn ẹ̀jẹ̀ mi mọ́. Mo fi ọkàn igbàgbọ́ jẹ ẹran Jésù. Nítorí a ti kọ ọ́ pé, Ẹran-ara Rẹ̀ jẹ́ oúnjẹ nítòtọ́. Mo jẹ ẹ́ báyì, kí nba lè jẹ pẹ̀lú Rẹ̀ nínú Ògo Rẹ̀. Bí mo ṣe njẹ́, tí mo sì tún nmu ẹran ara àti ẹ̀jẹ̀ Jésù Krístì Olúwa, mo sọ májẹ̀mú mi pẹ̀lú Rẹ̀ dọ̀tun, mo sì gba ìyè tó nbẹ nínú rẹ; nítorí a ti kọ ọ́ pé, ìyè nbẹ nínú ẹ̀jẹ̀. Nítorí nà, mo gba ìyè àti Ẹ̀mí Krístì sínú mi (Àmín).

ORIN ÌYÌN ÀTI ÌJỌ́SÌN

1. Ẹ ṣeun Bàbá fún àwọn anfàní àti ipèsè ẹ̀jẹ̀ Jésù.
2. Mo lo ẹ̀jẹ̀ Jésù sí gbogbo aìsàn tó farasin nínú ayé mi.
3. Mo wọ́n ẹ̀jẹ̀ Jésù sí àgọ́ ara mi – láti irun orí mi títí dé àtẹ́lẹsẹ̀ mi.
4. Mo gbé ẹ̀jẹ̀ Jésù dání gẹ́gẹ́ bí asà lòdì sí agbára aìsàn yòówù nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, a ti ràmípadà kúrò nínú gbogbo aìsàn.
6. Nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo gba iwòsàn.
7. Nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù, mo ní ìyè Ọlọ́run nínú mi.

8. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù dúró sí àárín èmi àti aìsàn yòówù.
9. Mo fi gbogbo iṣẹ́ òkùnkùn nínú ayé mi ré, kí wọ́n gbẹ títí dé gbòngbò nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù.
10. Mo fa obìrí ẹ̀jẹ̀ Jésù yípo mi, lòdì sí ọfà aìlèra.
11. Mo borí gbogbo ẹ̀mi aìlèra nípa agbára Ọ̀dọ́-Agùntàn.
12. Kòsí ẹ̀mí, agbára tàbí ẹ̀dá tí yóò lè fi aìsàn yòówù sínú ara mi nítorí a ti ràmípadà nípa ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Agùntàn.
13. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù sọ̀rọ̀ ìparun sórí gbogbo ohun ibi tó n dàgbàsókè nínú ayé mi.
14. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù sọ̀rọ̀ ìpóórá sórí gbogbo àìlera nínú ayé mi.
15. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù sọ̀rọ̀ alàfíà si gbogbo ẹ̀yà àgọ́ ara mi.
16. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù sọ̀rọ̀ iwòsàn si gbogbo ẹ̀yà àgọ́ ara mi.
17. Mo sọ gbogbo agbára ibi tó n gbógun lòdì sí ìlera mi di aláìlágbára nípa ẹ̀jẹ̀ Jésù.
18. Jẹ́ kí ẹ̀jẹ̀ Jésù ṣiṣẹ ìjákulẹ̀ sórí gbogbo aìsàn nínú ayé mi.
19. Mo gbé gbogbo ibi ìdúró agbára aìsàn yòówù dè nípa agbára ẹ̀jẹ̀ Jésù.
20. Mo mú ẹ̀jẹ̀ Jésù dání lòdì sí idàdúró òkùnkùn sí àwọn iyànu iwòsàn mi.
21. Mo mú ẹ̀jẹ̀ Jésù dání lòdì sí aìní ilèra pípé.

ORIN – ONÍṢÈGÙN NLÁ WÀ NÍYÌN

1. Oníṣègùn nlá wà níyìn,

Jésù abánídáro,
Ọ̀rọ̀ Rẹ̀ mú ni lára dá,
A gbọ́ ohùn ti Jésù

Ègbè
Ìrò dídún l’orin Séràf
Orúkọ dídùn lí ahọ́n
Orin tó dùn jùlọ ni,
Jésù, Jésù, Jésù

2. A fi gbogb’ẹ̣ṣẹ̀ rẹ jì ọ́
A gbọ́ ohùn ti Jésù
Rìn lọ s’ọ́run l’álafíà
Sì bá Jésù dé adé.

3. Gbogb’ògo fún Kríst’t’ó jìnde
Mo gbàgbọ́ nísisìyí:
Mo f’orúkọ Olùgbàlà,
Mo fẹ́ Orúkọ Jésù.

4. Orúkọ Rẹ̀ l’ẹ́rù mi lọ
Kò sí orúkọ míràn;
B’ọ́kàn mi ti nfẹ́ láti gbọ́
Orúkọ Rẹ̀ ‘yebíye